# ILANA ISE SAA KETA (SSS2)

| OSE | AKOONU ISE |
|---|---|
| Kin-in-ni: | Igbagbo Yoruba nipa aseyinwaye : Ohun ti aseyinwaye je, awon ohun ti o fi igbagbo Yoruba ninu aseyinwaye han. |
| Keji: | Ise owo abinibi ile Yoruba: Ohun ti ise owo je, awon ona ti ise owo abinibi pin si: ise agbe, ise ode, ose owo, ise ona. |
| Keta: | Leta gbefe ati aigbagbefe: Alaye lori irufe leta ti leta gbefe ati aigbagbefe je, awon ti a n ko won si ati igbese kiko won |
| Kerin: | Eto ebi: Ibi ti eto ebi ti bere, awon to n sakoso pelu Baale ni agboole |
| Karun-un: | Iwe litireso kika: Kika awon itan kan ninu iwe 'Akojopo Alo Apagbe' |
| Kefa: | Idanwo ilaji saa / Igbagbo Yoruba nipa Olodumare: Eni ti Yoruba n pe ni Olodumare, orisirisi oruko ti a mo o si |
| Keje: | Aroko pipa: Ohun ti aroko je, awon ohun ti a le fi paroko ati itumo won |
| Kejo: | Awon orisa ile Yoruba: Awon ti a n pe ni orisa ati idi ti a fi n pe won bee, alaye lori orisa bii obatala, orunmila, sango ati bee bee lo. |
| Kesan-an: | Eto ogun jije: Ohun ti ogun je, awon ohun ti eeyan le je logun, awon ona ti a n gba lati pin ogun |
| Kewaa: | Apejuwe iro konsonanti: Ohun ti konsonanti je, sise apejuwe awon iro konsonanti nipa lilo; ibi isenupe, ona isenupe, ipo afase, ipo alafo tan-an-na |
| Kokanla: | Atunyewo ise saa |
| Kejila: | Idanwo ipari saa |

## IGBAGBO YORUBA NIPA ASEYINWAYE

Awon Yoruba gbagbo pe iye n be leyin iku, eyi ni won n pe ni aseyinwaye . Won gbagbo wi pe ara eeyan lo maa n ku, emi kii ku ati wi pe eni ti o ku le pada was aye lorisirisi ona.

## AWON OHUN TO N FI IGBAGBO NINU ASEYINWAYE HAN

1. Adiye irana: Awon Yoruba maa n powe pe 'Adie irana kii se eran ajegbe'. Ninu isinku isenbaye, abigbeyin oku tabi omo-omo kan ni yoo maa tu iye ara adiye saaju oku, lati ra ona ninu irinajo re lo si ibomiran. Won gbagbo pe oku n lo si irinajo miiran ni.
2. Ounje ona orun: Bi awon Yoruba ba n sin oku agbalagba, ti won ba ti te si iboji tan,won maa te aso lorisiirisii ti oku le wo nigba ti o ba de ibomiran ti o n lo. Bakan naa ni won n ko orisii ounje ati ipanu bii eko akasu, olele, taba, obi ati bee bee lo sinu iboji.
3. Abobaku: Nigba ti won ba n sinku oba laye atijo, won maa n sin awon eru die po mo on niluu Oyo. Awon eru ti a sin laaye pelu oba ni a n pe ni abobaku( a-ba-oba-ku). Won n se eyi ki oba le ri awon eeyan ran nise.
4. Egungun: Igbagbo ninu aseyinwaye lo muesin egungun waye. Bi agbalagba okunrin kan ba ti ku ni awon ebi re yoo ti daso egungun fun un ni ireti pe won yoo maa bo o nigba gbogbo ni iranti re. Odoodun ni won a maa bo eegun yii.
5. Ebo riru si awon oku orun: Igbagbo ninu aseyinwaye lo n mu awon babalawo ka ebo fun awon eeyan lati ru si awon oku orun, nigba ti won ba wa nnkan, ki ohun ti won n fe le yori si rere. Lode oni, awon eeyan maa n yi eyin oku pada ni ireti pe won ku sugbon pee mi won wa titi laelae.
6. Oruko lati fi ranti oku: Igbagbo Yoruba ninu aseyinwaye han ninu oruko ti won maa n so awon omo ti won ba bi leyin ti oku naa ba ku. Bi okunrin kan ba dagba ti o ku, ti obinrin re tabi iyawo ile si bi okunrin, won n so omo bee ni Babajide, Babatunde tabi Babatunji. Bi o ba se obinrin agbalagba lo ku ti won si bimo obinrin leyin oku, won a so omo bee ni Iyabode, Yetunde, Yewande, Yejide ati bee bee lo.
7. Abiku: Igbagbo ninu aseyinwaye tun han ninu oruko abiku ti awon Yoruba n somo ti o ba ku laipe ojo to tun pada wa. Won n so oruko abiku bii Kukoyi, Igbekoyi, Akisatan, Durosinmi ati bee bee lo.
8. Akudaaya: Yoruba gbagbo pe eni ti o ba ku laipe ojo kii lo sinmi. Iru eni naa ma tun pada saye lati lo maa gbe ilu miiran to jina si ibi ti won ti mo on. Oun ni won fi maa n ni won ri won ni oja niluu to jina rere ati awon ibomiran.
9. Ikini fun awon omolooku: Igbagbo Yoruba ninu aseyinwaye lo n mu awon ikini ti won n ki awon omolooku waye. Apeere ikini ni:
   i. 'Oku yoo wole de yin o'
   ii. 'Iwaju to doju ko yoo dara, eyin to fi sile ko ni baje'.

   Won a tun maa so fun oku pe:

   i. ‘Bi o ba dorun, ki oko re’
   ii. Ma jokun, ma jekolo, ohun ti won ba n je lorun ni ki o ba won je’
10. Igbagbo ninu aseyinwaye tun maa n mu ki oku orun be awon eniyan re wo loju ala.

ISE SISE

Nje igbagbo ninu aseyinwaye si wa lode oni? Fi apeere meji gbe idahun re lese.